To the Chief Secretary to the Govt

Ki l'Eleko ṣe, Lọya lamọmọ to nmọ'gbo ojugun.


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI No 287 SATURDAY AUGUST 11, 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakureghe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi [illegible] Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


SLOAN'S
N&B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
Medicine Dealers
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exercise
LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
D Earl S Sloan
TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor.*—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹta | 6/- | 6/6d | 7/- |
| Osu mẹta | 3/- | 3/6d | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

OWO-ORI MBI IGE O MBI ADUBI.

Irohin kan ni lati Ilu Wari pe nigbati awọn Alaṣẹ Ijọba de Ilu kan ti nwọn npe ni Ilado leti Wari lati lọ ṣe abere ẹhin Owo-Ori sisan lọwọ awọn ara ilu ibẹ a gbọ pe biotilẹjẹpe awọn oloye diẹ pẹlu awọn enia wọn lo san nṣe ni ọgọrọ ninu awọn enia fi ilu silẹ salọ sinu igbẹ gẹgẹ bi a ti gbọ ọrọ na si.

AWỌN AJẸJA NDA NKAN NI 'NDE.

A sọ fun ni pe awọn Aganyin ti nwọn ndẹja ni Okun ṣe ọdun kan ni *Sunday* ọsẹ tokọja a ko le ṣẹṣẹ sọ bi ẹja ti nwọn lo fi se kọtọ Ọbẹ ti pọ to kini a ti nṣe ori ni ile iku.

DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ Kekere Awo.

ONI-POKITI KẸLẸKẸLẸ O!

Nigbakugba li a ma nsaba ṣalabapade iwa-eri ti awọn Oni-pokiti kan ma nhu nipa gbigbe Pokiti ti Igbọnsẹ—ti igbọnsẹ inu rẹ si gbangba ode ti o si ma nda orun pa awọn enia—Bẹni a ṣe alabapade Pokiti kan ti o ni Igbọnsẹ ninu ti nwọn yibiti rẹ si oju Gọta kan ni Phoenix Lane larin ọsẹ to kọja, ti o jẹ wipe gbogbo ẹniti o nrekọja nibẹ lo nfi ọwọ bo imu wọn; irufẹ iwa ṣiṣe eri si arin ilu bayi ti jẹ? Nitorina ki awọn Oni-Pokiti ti o nsaba ṣe bẹ lọ ṣe kẹlẹkẹlẹ o nitori ọjọ ti ọwọ ba tẹ wọn, nwọn a gbọn.

AWỌN DẸRẸBA-MỌTO.

Itumọ wipe ti o ba di ni idaji owurọ ki awọn Dẹrẹba Mọto miran ti ma npa Fitila Mọto wọn, lẹhin ti o jẹ wipe Ina-ọba koi ti ku? Bẹ bi nwọn ba ti tan Ina Ọba ni ori alẹ ni olukuluku wọn yio ti bu ina si Fitila Mọto wọn awa ṣebi ina ti Ọba ni nwọn nwo tan ina tiwọn—awa ro wipe ẹtọ ti o nmu wọn sure tan ina sinu Mọto wọn nigbati ina ba ti wọ Atupa Ọba ni ori alẹ mu wọn ṣe suru titi ina Ọba yio fi ku ni owurọ.

TOWN COUNCIL.

A tun ke si awọn Alaṣẹ-ilu ki nwọn jọwọ ba wọn ṣe oju Gọta kekere kan si adugbo kan ti o njẹ Macaulay Steet lati le ma dabobo omi-orun ti nwọn ma nda si ojude Adugbo na lalalẹ gẹgẹbi a ti sọ ni lọlọyi.

HABATIALAPA.

A gbọ wipe nwọn ṣe ere aladun kan (Concert) ni gbangba Kirsten ni ibiti a mọ ni ile Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E., F.R.G.S., ni ọjọ Alamisi to kọja lọhun—ere na dun yungba-yungba ẹnikeji.

SHAIKHU BAKARE IKANDU.

Gbukẹ li a gbọ ti iku Alufa Bakare Ikandu ni owurọ ọjọ Satide ti o kọja, nwọn si ṣe sintura rẹ eyiyi ni isinku ni ọsan ọjọ Satide na, eyiti a gbọ wipe Lemọmu Ligali lo ba wọn sin oku rẹ de itẹ Oke Suna gẹgẹbi ọmọ ẹhin rẹ—a ki gbogbo ọmọ oloku, ki Ọlọrun dẹlẹ fun baba wọn o.

IMỌRAN SI ẸGBẸ DẸMỌ.

Ekeji.

Gẹgẹbi a ti sọ lọsẹ to kọja ti a ba yan ẹnikan lara awọn olotu ẹgbẹ ti a ba fi Alaga ẹgbẹ ti adugbo nyẹn, dajudaju a o ma ri oye ti o dara, bẹni gbogbo nkan yio si ma lọ si dede, ohun ti o ba ru ni loju nipa alamọri ẹgbẹ yi a le fi si iwaju Alaga ti a yan, ki o si la ni loye ọran na.

Adugbo mẹwa le yan ẹnikan na ni Alaga ni iwọn igbati o ba ti jẹ onile yi ko mọ ohun ti onile yi nse ni, ohun ti o wa nibẹ ni wipe ọran na ṣubu si ori aseko gan, nitori bi adugbo meji mẹta ba yan ẹnikanna ni Alaga gẹgẹbi a ti sọ ni iṣaju wipe ko laifi, Alaga na lo ma yan aseko ti yio yẹ ye olukuluku lọwọ, ambọsi-bọsi awọn enia ko wọn to ohun ti Alaga ko fi nj le kari adugbo kankan ni gbogbo ibiti ẹka ẹgbẹ Dẹmọ gbe ta de ni arin ilẹ yi.

Ipade ẹgbẹ ti Ẹhingbẹti yio dabi Gbongbo tabi igi lẹhin ọgba gẹgẹbi awọn ti ni lati mọ—ti a ba ni ọna ti a ma la silẹ bi ẹgbẹ ko tilẹ pe ni Ile

Afari-ogun ni ẹkan lọdun ko ni laifi danin-danin, awa tikalarawa ko tilẹ ni mọ ala pipe ẹgbẹ tikalararẹ. Mo fi imoran yi si iwaju ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni, ṣugbọn nkan pataki lo jẹ bi ẹ ba le fi si aniyan.

### PA GUNNUNGUN BỌ'FA!

Diẹ lo ku ki iya kan ṣe agbako ni opopo Victoria ni ọjọ Tuesday nigbati ọmọ eṣu kan ni on ngun kẹkẹ-ologere kan ti o si gbọn jinni-jinni loju Titi, eyiti o fẹ fi kọlu iya na nigbati Mọto mbọ.

### ẸMU TABI OGURỌ?

Ọkunrin wonpapa kan lo nṣe gọṣọgọṣu ni apa ọna Oluwole ni ọsẹ to kọja ti o ni ọti npa on, ti o si nfi di alafia ilu lọwọ loju awọn enia—kẹlẹkẹlẹ o!!

### ALAJI ADAMỌ.

Gbukẹ li a gbọ ti iku Alaji Adamọ ni ile rẹ ni ẹba Mọṣalaṣi Jimọ ni ọjọ Wednesday ọsẹ yi—a ki ẹbi, aya ati ọmọ nwọn ku ajalu na, ki O si forijin ni.

### KEIFA LABARI?

Girigiri ti a ri awọn ọkunrin ati obinrin kan ni owurọ ọjọ Alaruba ọsẹ yi ti nwọn nda, lọ lo mu wa ṣe abere—ẹhin eyiti a gbọ wipe awọn ara oke-Arin ni ati pe nipa ọpẹ-alaiye ile kan ni nwọn nlọ fun—ọhun a dara o! A o fi imu finlẹ daradara ati gbọ gasikia ki a to mọ ohun ti ao ṣe si i.

---

### ORI IV.

## IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KẸSAN.

A ti sọ ti bi iṣẹ ṣiṣe ti jẹ ẹkọ; o si tun jẹ eyiti ikọ ni ni iwa pẹlu. Ani iṣẹ ti ko tilẹ ni ere, bi o ba ti jẹ iṣẹ ṣa, o san ju ki enia wa gbunduku lọ—bi o ba ti ṣe pe iṣẹ na jẹ eyiti ikọ ni ni ọna ti a fi ilo ọgbọn ori ẹni, ti eyi a si jẹ ipilẹ ọna ti imu iṣẹ gun.

Iṣẹ ṣiṣe a kọ ni, ni eto. A mu ni mọ lati ma lo akoko danu ati lati fi asiko si ohun gbogbo ti a ri iṣe.

Bi ara enia ba si ti mọ iṣẹ ti o tọ lati ṣe ko ni si asiko kan ti a o lo danu; bi isimi ba si de, a fi taratara gbadun rẹ.

"Otọ ni Coleridge sọ pe, bi a ba nsọ pe ọlẹ enia a ma pa akoko loku, a ko ṣi sọ nigbana ti a ba sọ pe ẹnia ti o ba mọ eto a sọ akoko di aye, a sọ ọ di nkan, ki iṣe pe a pe eyi ni iṣẹ nikan ni, ṣugbọn a mọ o ni iṣẹ pẹlu. Gbogbo akoko ni ifi eto si ti isi sọ di nkan; nipa eyi, a mu akoko eyiti ki iduro de ẹnikan ti a si rekọja lọ, ṣe ohun rere koni-gbagbe silẹ".

"Ẹni rere ati olotitọ enia ti o tọ ọna yi ti eto si ja ja, ni gasikiya, on ni o lo igba, igba ko lo o".

"Awọn ọjọ, oṣu ati odun rẹ, bi ati awọn iṣẹ ti o ṣe, iwọnyi yio kẹhin aiye, nwọn yio si wa bakana nigbati akoko papa ko ba si mọ".

---

### IROHIN ỌLADUNJOYE ỌLỌLA ỌBA ODE JẸBU RẸMỌ.

---

Mo ju ba o, ẹnyin Alagba Ọlọlajulọ,

Ẹ jowọ ẹ ba lọ ka iwe Romu ori 12 ẹsẹ kẹsan ati kẹwa.

Ẹnikan sọrọ ninu Iwe irohin *Nigerian Advocate* wipe Waranti ti nwọn fi mu Ọba Ode ko dara, ti o si nba Ọlọla Awujalẹ ati *Resident* Ọlọla wipe ko ri bẹ.

Gẹgẹ bi ofin Ibilẹ o dabi ẹni pe mo gbọ pe won wipe wọn ko tun fẹ ni Ọba mọ.

*Resident* Ọlọla Amofin ni dajudaju ni oju mi nitorina Waranti ti nwọn fi mu Ọba ni Ode o to nitori ofin ko mo ẹnikan sọtọ.

Ẹnyin Alagba Ọlọla nla nkan ni mo rope o nja ni ode nipa Oye Ọba Ode nitori Ọba Alaiye Ode Oshinloye Ọlọla nigbati o nfẹ ku o sọ si eti gbọ Ọgbẹni Gbọdiyan ati awọn ọpọlọpọ enia pe Mr. Adeoshin ni Ọba kan bi on ba lọ si ile. Eyini nigbati o ba ku. Aṣẹ Oshinloye Ọlọla Ọba Alaiye Ode ti nwọn rọ on ni mo rope o mu rukerudo yi wa si ode titi doni. Nitorina nigbati Gbadebọ Ọba Abẹokuta Ọlọla nla lọ si Ilu Oyinbo o fi Ademọla Ọlọla han wọn ni ọhun pe bi on ba ku o ni Ademọla ni Ọba kan lati jẹ lẹhin on ni Ọba Abẹokuta. Ogbẹni J. K. Coker Ọlọla ko jẹki aṣẹ Gbadebọ Ọlọla yẹn yipada rara.

Mo juba ẹnyin Alagba emi J. A. O. Shomade emi ikan ninu ọmọ Alaperu mo fi ọwọ ati itẹriba bẹ nyin, ẹnyin Ijọba Igẹsi Ile ẹwọn tabi tubu ti Qeen Victoria fun Ijẹbu Rẹmọ ati Doctor ati Jailer ati warder a kọ mọ idi bi gbogbo rẹ tiṣe

kuro ni Ishagamu rara o, bẹni Qeen Victoria fi awọn yi ṣe Ọla fun Ijẹbu Rẹmọ ni, nitori ọmọ ni Shagamu jẹ ni ọdọ awọn Ijọba Igẹsi gẹgẹ bi awọn Eko ti ni Ọpa Adehun pẹlu Ijọba Igẹsi bẹ gẹgẹ ni gbogbo Rẹmọ mẹtata ni Ọpa Adehun ni Shagamu Rẹmọ pẹlu Ijọba Igẹsi o dun mi pe emi ko mọ No. nitorina a bẹ awọn Ijọba Igẹsi ki wọn tun fun wa ni Ile ẹwọn tabi tubu, ati Doctor ati Warder ati Waya ati Telegram titi de Ishagamu titi de Ipẹru ati Post Office mo fi ọwọ ati itẹriba bẹ nyin, ẹnyin Ijọba Igẹsi ti Eko nitori ọmọ rere ni Ijẹbu Rẹmọ ni ọdọ Qeen Victoria Ọlọla nitorina ohun ti nwọn fi da wọn ni Ọla wọn o ni lati gba kuro lọwọ wọn mọ.

Ẹniti aigbọn pa li o pọ ẹniti ọgbọn pa ko to—nkan.

Arun nla ni nigbati enia ko ba mọ iru ipo ti o wa. Ṣugbọn gbọngbọn kan ko si afi ẹniti o nfẹ ti ararẹ.

Emi ni ti nyin

J. A. O. SHOMADE.

## IROHIN ILE-IFẸ.

Gbogbo ara ile Ifẹ ni yio ṣe akiyesi ni lọlọyi, wipe awọn ọdọmokunrin alapa-maṣiṣẹ, ni wọn nrin irin agba moye kakiri ile Ifẹ ti nwọn si jẹ ọmọ Jaguda, ko ṣa si ilu ti Jaguda ko bimọ si, ko si ẹnti ko gbọ wipe ọkan ninu awọn ọmọ Jaguda yi ja Ọgbẹni Joseph Kabiyawn lole, o gbe owo Ogbẹni yi, nigbati wọn pari ẹjọ rẹ, adajọ ju si ẹwọn odun kan. Igbẹhin ọlọṣa re yi o.

" Ẹwọn ki pa ọbọ ṣugbọn a yin nidi. " Ẹnikeji ti orukọ rẹ njẹ Joshua ti o wa ni Koto Atiba iyẹn la ji Pako *Planks* ohun to ma fi pako ṣe ko yeni, bo ma ta ninu kiko re lati ibi kan si ibi keji nilẹ yio mọ ti, ẹru ki pa ibakasiẹ ṣugbọn ọrun rẹ yio wọn " nigbati nwọn ṣe ẹjọ Joshua ol ṣa tan adajo ni ko lọ si ẹwọn oṣu mẹfẹ, ẹwọn oṣu mẹfa ko pa ni lebi, ṣugbọn a lọ oluwarẹ funfun, ni arọ ijọ kini oṣu yi, ni wọn mu gende Joshua yi lọ si ẹwọn ni Agodi Ibadan.

Ninu gbogbo wọnyi, ọwọ tun tẹ ikẹta eyi to wa ninu Ejiran nisisi, ti wọn ko ti pari ẹjọ rẹ, iyẹn tun jẹ alejo to wa ni agbole wọn ni ole, o ji ni ponwun meji abọ ati kẹkẹ ologere *cycle* eyiti wọn nwa, ti wọn si ri ni yara rẹ, loni ijọ keji oṣu yi ni wọn yio pari ẹjọ rẹ, bi wọn ba ti pari rẹ si, ẹ si ma gbọ—Njẹ irohin yi ko ni ba ọpọlọpọ ninu jẹ wipe ole ṣẹ npọ ni ile Ifẹ, ilu ti ẹnikẹni mọ wipe ohun eri ati ẹgbin ko si ninu rẹ, nitori na a ke si ẹnyin Kansulu ile Ifẹ ati Ọba Ọni, kabiyesi bi ẹ ma gba awọn to ma jẹ ọlọpa-inu si ile Ifẹ ko ma jẹ ki awọn akẹran le gbilẹ si ile Ifẹ nipa iṣẹ buburu wọnyi.

Awọn ara Mọdakẹkẹ wọn ṣe ọdun Egungun, wọn si ti pari rẹ, anu ṣe ni wipe ninu ojo ni wọn ṣe ọdun yi, ojo ko dara fun wọn rara, ninu ọsẹ kan, ọjọ kan pere ni wọn ri to fi oju silẹ daradara ti wọn si fi ṣere gbadun. Odua ki o fi ọpọlpọ miran han awọn ara Mọdakẹkẹ yi.

Gẹgẹbi aṣa Ọyọ-Ifẹ ti wọn nṣe Egungun wọn ni aṣiri kakiri igboro, wọn ṣe, ojo si mara duro fun wọn, wọn si gbadun ọdun wọn na.

Baba wa Ọni Ifẹ ati D.O., won da awọn ẹgbẹ *Tennis Club* Ifẹ ni ọla nipa fifun wọn ni ilẹ ni Lagere ni ọja Lagere fun a ti ma ṣere wọn *Tennis ground* ilẹ ti Ọni fun won yi wa ni ẹba igi ọsan o fẹ doju ko ile ọja Prince Adeyẹmi leti agbala awọn Ọyọ adọjọ ni ibu ati adọjọ ni oro, 150 x 150.—Adura wa ni ki Ọbaki pẹ fun inu rere lati fun wa nilẹ to tobi ba yi.—Ina egbẹ na ko ni ku—kabiyesi—a si ki D. O. papa o ṣe pupọ, a ba ile nire. Ẹnyin ọmọ Ẹgbẹ o di ọwọ nyin nipa titunṣe ilẹ yi.

Anu ṣe wa pupọ wipe Catichist wa Ọgbẹni Ibikunle fi ilu silẹ o lọ si Oshogbo lọdọ Dokita oyinbo fun itọju nitori ara rẹ ti ko le. Adura wa nipe ki Ọlọrun mu Ọgbẹni Ibikunle yi bọ wa fun wa ni alafia. Ogbeni Ibikunle yi lo wa St. Peter Church ti Irẹmọ, a si tun ni lati sọ gẹgẹbi awọn ọdọmọkunrin ti ngbin yanju owo dida nipa kiko ile Ọlọrun titun eyiti wọn ti nda bọ Owo na si ti njọ ju nisisiyi, Oluwa ko bu si apo ti owo na ti nwa, ki Oluwa si ṣina iṣẹ rere fun nyin, kiko ile Ọlọrun ko tẹrẹ ko si pari ni oju nyin—amin.

Ọsẹ to mbọ yi ni ijo kejila oṣu yi ni agbara Olodumare ni ọsẹ ti Pastorate Anniversary eyiti Archdeacon I. A. Jacobson Ogunbiyi yio ṣe iwasu ọjọ na ni iya Church iyẹn ile-isin Aiyetoro ti o jẹ iya ilana-isin gbogbo ile Ifẹ, awọn aṣoju gbogbo Ilesha yio pesẹ, awọn gbogbo ijọ ile Ifẹ si ti nmura lati gba gbogbo awọn alejo wọnyi sọwọ sẹsẹ ati Ardchdeacon ti o ti Eko wa. Ojo-ọsẹ yi yio jẹ ọjọ pataki, ki Oluwa ki o mu ọjọ ro, ki o si mu awọn ero wọnyi wa ba wa ni alafia, ki nkan ma si ṣe awọn ti wọn o fi silẹ nile olukuluku won, amin

O tu si wa leti finrin wipe Ọgbẹn Titus Obe ọmọ ile Awọfin ti ile Ifẹ da kan lọ si Eko, ati wipe Ọba wa Ọni lo ran lọ lati la wo arakunrin rẹ E. T. Adewọyan Coker to wa ni ile alarun ni Eko nikawọ Dokita Gray, a si gbọ wipe Obe ba Ọgbeni Coker ni alafi ni ọjọ Satide ijọ kẹrin oṣu August ati Iyawo rẹ Felicia ati ọmọ rẹ Abiodun wipe ko si nkankan lara wọn. Nitori na Dun-Serki gbe ra nilẹ ko dide, ma fi oju wa si ọna mọ

titi lç, nitori a fo rẹ şi silẹ larin tẹgbẹ tọgba fun iwa rere ati imọran uyin fun wa nigbagbogbo,

" Wọn ni iwọ oro, kilo şe to nke a ke 'dabọ bẹ, o ni ohun to nfi on ni ko jẹ, ki owe na jẹ ti nyin, "

O ta si leti finrin ni arọ yi *Thursday* ijọ keji oşu yi ni ita Otutu wipe Ọgbẹni E. T. Adewoyin Coker yio fi Eko silẹ ni ọjọ *Thursday* ijọ kẹrindinlogun oşu yi, o mbọ wa si ile Ifẹ, bi eyi ba jẹ o tọ, a nreti iwe lati ọwọ Ọgbẹni wa yi, ki a le ba pade rẹ.

---

## ONI LAJA TI FI ORI GBOGBO, TIRẸ MA DẸ PỌ KẸ !

Ni ọsan ojọ *Monday* ọsẹ yi ti nşe ọjọ *Bank holiday*, 6-8-28, Ogbẹni kan bẹrẹ si ja pẹlu awọn Ọlọkọ *canoe*, ohun ti a gbọ pe o padi ija yi ni pe, Ọgbẹni kan ba ọkọ wọn wa lati Ikorodu nigbati nwọn de Ebute Idunmagbo nwọn gunlẹ pẹlu ọkunrin na Ọgbẹni na dẹ lọ bamubamu laiko san owo fun ọlọkọ, nigbati o di ojo keji awọn ọloko ri Ọgbẹni na, nwọn bere pe kini şe ti o ko dẹ sanwo lana ko to lọ, arakunrin ibẹni ẹnikeji gbija to dapara lu awọn ọlọkọ bayi pe kai ma da wọn lohun owo kini, ori wọn lo fọ, ebi ko pa Geşa o ni on ko jẹ ori Oyọ, ebi pa sule o jẹ ọbo ka wi ka fọ *Inspector of Police* de ati ọlọpa kan si gba wọn lọ si tesan.

## GASA IGIDA ! ABI'AMỌ Ẹ KU RỌJU !!

A gbọ pe awọn ti wọn nba ọkọ ilẹ rin bọ lọjọ kanna yi şe ijamba lọpọ lopọ, a gbọ pe awọn meji Lagbado ẹnikan ni Agege, a gbọ pe nwọn gbe wọn lọ si ile Dokita ni ọdan, kini ohun ti o ya ni lẹnu ninu rẹ, elu oku koku jẹ o nlọ o mu lamu-lamu a gbọ pe bi Ọgbẹni kan ti fẹ bẹ silẹ lati inu ọkọ ọwọ rẹ ko ja bẹni ọkọ nwọ lọ rẹrẹ titi o fi bo loju ati ni imu ki awọn ara teşan to gbe dide pẹlu igbaju ati igbamu, a ko ri si eyi ni, nigbati enia fi ara pa tan ti ẹ dẹ tuu nlu pẹlu. Oşe ! igimada o,'pẹlu iwa ailanu ti awọn enia kenia wọnyi nhu.

Ẹ o riro ti ọjọ ba to, ẹ o jihin niwaju Onişẹnla.

TẸNIMASUNWỌN.

---

## KOTU ASSIZE

Orukọ awọn ẹniti Kotu, Assize nbarojọ lati ibẹrẹ ọsẹ yi ni wọnyi, pẹlu ẹsun ẹsẹ ti ofin fi wọn sun.

| | Orukọ. | Ẹsun. |
|---|---|---|
| 1. | Şanusi Abinupaleka | Pe o ji £50 owo Malam Dawodu. |
| 2. | Jacob Kẹhinde Coker | |
| | David Ayọdele Hughes | Pe nwọn lo £500 ti Fred Williams ologbe fi si itoju wọn fun nkan miran ni ọna ti ko ba iwe ti ologbe şe silẹ mu |
| 3. | Ben. Adegoke | Pe o pa Amọdu kan o si wa mọto ni iwa " bole ya ki o ya. " |
| 4. | Apalara Bashua | Pe o pa Ayọdele Bashua kan. |
| 5. | Jacob Kẹhinde Coker | Pe o lo £200 owo ti Fred Williams ologbe fi si itọju rẹ, fun nkan miran ni ọna ti ko ba iwe ti ologbe şe silẹ mu. |
| 6. | Lamina Sanni Kọtun | Pe o da iwe Akanti awọn G B. Olivant ru |
| 7. | (1) Wusu Amusa<br>(2) Oke<br>(3) Disu<br>(4) John Kina<br>(5) Ọkọosi<br>(6) Wusu Jamba<br>(7) Nupe<br>(8) Kiripe<br>(9) Jẹbu | Pe nwọn fo 'le Abu kan ni Poti pe nwọn ji aşọ Abu, Mọmọdu ati Yesufu, pe nwọn pa kọmbodu kan lara. |
| 8. | Lawani Mọgaji | Pe o fi ipa fe ọm de binrin Ajisatu ọmọ bi ọlọdun meje. |
| 9. | (1) Yesufu Lawani<br>(2) Salami Adeyẹmọ | Pe nwon fi ko korọ eru tabi ẹro miran şi nkan bi apoti pe nwọn di mọpo lati ji nkan Ladeji Yesufu, pe nwọn ni ohun ija lai ni ọwọ ofin ninu. |
| 10. | Mark Bisset Toko | Pe o gba £1 10 lọwọ Archmorind Fashina lọna eru. |
| 11. | Mark Bisset Toko | Pe o gba £2 10 lọwọ Aje lọna eru |
| 12. | " " " | Pe o fi eru gba £5 lọwọ Cecilia ko sọ kokan. |

| | | |
|---|---|---|
| | " " " | Pe o di Şaji ọlọpa Lawani Latunji ọwọ lẹnu işẹ rẹ. |
| | " " " | Pe o fi ọwọ F. H. Henderson si iwe kan lọna eru. |
| 13. | Baramọ Dẹnde Ashimcu Gbadamasi | |
| 14. | Belo Bakare Gbadamasi Olowoshile Ashimcu | |
| 15. | (1) Sina (2) Yesufu (3) Ashimọu (4) Gbadamasi Olowoshile (5) Tunde | |
| 16. | (1) Belo Bakare (2) Gbadamọsi Olowoshile (3) Ashimọu. | |
| 17. | (1) Alimi (2) Ashimọu (3) Gbadamọsi Olowoshile. | |
| 18 | Afọsefu. | |

*Gẹgẹbi a ti nbẹ Gazelle wa bọ, ninu ikanna ni a nlunọ yi.*

iv Ani lati tẹ aşẹ ninu iwe irohin' ijọba (Nigeria Gazette) asi ni lati mu lo ni ijọ ti Gomina ba fi aşẹ si, tabi adele to wun ko jẹ ni asiko to ba wa gẹgẹ bi Olotu ijọba ti Nigeria nipa kike sode ninu iwe irohin ijọba yi ati Gomina ati ẹniti o wun ko jẹ ni lati la nọ fun titẹ sode aşẹ yi nibiti ewon ko jẹ ati ni ọna bayi ati fun asiko si akoko ni eyi ti o ro wipe oto lati tẹ tabi sọfun ilu ati gbogbo Nigeria.

v. Alayelowa le ni akoko to wun ko jẹ parẹ tabi yi tabi fifi kun tabi kio yi aşẹ yi pada.

And the Right Honourable Leopold Charles Maurice Stennett Amery, one of his Majesty's Principal Secretaries of State, is to give the necessary directions here in accordingly.

M. P. A. HANKEY.

## A PROCLAMATION.

IWE AKEDE IJOBA.

Lati owọ Ọlọla Gomina Graeme Thomson, G.C.M.G., K.C.B., Gomina ati alaşẹ gbogbo ilu ati ẹkun Nigeria.

Nipa aşẹ igbimọ ti ọjọ kọkanlelogun oşu November, 1922, ati eyi ti a si mọ gẹgẹbi igbimọ aşofin ti Nigeria, aşẹ Igbimọ ti 1922, ti a fi aye silẹ fun ati şe idasilẹ igbimọ aşofin fun ilu ati gbogbo ẹku Nigeria ti a si ni lati mọ gẹgẹ bi igbimọ aşofin ti Nigeria.

Ati nipa aşẹ miran si ninu igbimọ ti ojọ kẹfa oşu February 1928 ati eyiti asi mọ gẹgẹ bi Nigeria (Igbimọ Aşofin) ati aşẹ ninu Igbimmọ 1928, ati si ati eyi aye ti aşe nipa dida igbimọ Aşofin kan na yi.

Ati nipa ẹsẹ kẹrin ti eto Igbimọ Aşofin ti Nigeria, aşe ninu Igbimọ ti 1928, ti wọn paşẹ wipe Igbimọ Aşofin ti Nigeria na, ati aşẹ ti Igbimọ 1928 ni lati mu şẹ ni ojọ ti Gomina ba fi si tabi igbakeji bi Olotu Ijọba ni asiko na, nipa ki kede ninu Gazette ti Nigeria.

Nitori na sẹ, Emi Graeme Thompson, G.C.M.G., K.C.B., Gomina ati Alaşẹ Ilu ati gbogbo ẹku Nigeria, paşẹ nipa fifi ọjọ kerindilogun oşu May 1928, gẹge bi ojọ ti Igbimọ Aşofin ti Nigeria na nipa aşẹ ninu Igbimọ 1928 ni lati mu şişẹ, ti ofin na si di lilo—

Nipa aşẹ owọ mi ati otitẹ Ilu ati gbogbo ẹku Nigeria ni oni ijọ kẹrindilogun oşu May 1298.

*Ao ma ba bọ.*

Emi ni ti nyin nitoto.

ENIA KO DA BI ALLAH.

## ỌLỌYA KI JẸ AGBO.

Iya Ọloya kan berẹ si sọ kakiri ni apa odo Oluşi ninu ọsẹ yi pe on dupẹ pe nwọn ko fi on si ẹwọn gẹgẹ bi awon kan ti nba on jẹ pe nwon fi on si ẹwọn o ni wọn ko fi on si ẹwọn, ilu on ni on nlọ.


## KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fe şe ariya ti Iyawo lo sibe, bi o fẹ şe Wolmọ lọ sibẹ, bi o fẹ şe ariya nipa ti oku lo sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

*EKO AKETE*

EKO, SATURDAY, AUGUST 11, 1928.

## KI L' ELEKO ṢE LỌYA LA MỌMỌ, TO NMỌ'GBO OJUGUN?

Iwe kan ti Lọya kan kọ sinu Iwe-irohin ojojumọ *Nigerian Daily Times* ni Satide tokọja nipasẹ ọrọ *Prince* Eṣugbayi Eleko ko ni ṣai ya pupọ enia ti o ba kà lẹnu, irufẹ ivalẹnu ti a nsọ nivi, kini Lọya rito ki o to pe ẹsin lẹrọnko. Ninu iwe rẹ, Lọya yi sọ eyiti o ṣe sọ o sọ eyiti ko ṣe sọ, eyiti o si jẹ akiyesi pataki ninu rẹ niyi, Lọya yi laiṣe Adajọ, laiṣe Kotu, nsọ kantankantan bi epo gbigbona pe ki a tilẹ sọpe Eleko yio bọ wa si ilẹyi o ni yio to iwọn ọdun mẹrindilogun abọ; ohun ti o si ni o mu on sọ bẹ nipe ki nwọn to ro ẹjọ na tan eyiti o sọpe yio gba ọpọlọpọ ọdun ni riro nibi ati ni Kotu Abẹsẹ Ọba King ni Ilu Oyinbo. Lọya na tilẹ gboju gbaya sọpe on ko ni tanmọ pe wiwa Eleko si igboro ilẹyi le jẹ nkan ti o le ya bẹ.

Ọrọ re o, ẹnyin ara ilu: ibere ti a le bere nipe Lọya ti o kọ irufẹ iwe "Aramu" yi Enia dudu ni tabi Oyinbo? Nitoripe a ko tanmọ pe Oyinbo ni, nitoripe o ṣoro ki ẹdun ọrọ Eleko ti o ndun gbogbo ilu nisisiyi je ọrọ ẹdun Oyinbo: nitorina ni a ṣe sọpe Enia Dudu ni Lọya ti o kọ iwe na: ẹ ko wa ti bi awa arawa ti ngbe ara wa fun gbogbo aiye lona yi: be ilẹ Eko ti Ọba Dosunmu baba *Prince* Eṣugbayi Eleko fiíun Ijọba Gẹsi, ni Lọya yi ma nlẹ, o ma si nṣiṣẹ owo ni ilu Eko kanna yi, o nṣanfani nibẹ pẹlu, sibẹsibẹ lori gbogbo eyi, ni Lọya na si jẹ kumoyo tan ti o nsọrọ ai... Eko Eleko ti o je ọmọ Onilẹ ti Lọya yi nṣẹ... ṣora ninu rè, Ori *Prince* Eṣugbayi Eleko ti ko ṣẹ Lọya yi ti ko si ro o ko ni ṣaibi dandan, epe kọ.

Ewo ni Lọya na tilẹ ru ti o ... lorin lori ẹjọ ẹlẹjọ bayi, ọrọ-ọlọrọ ṣa ni ... si, a ṣebi irufẹ ọrọ kọrọ bayi ni awọn kan nma sọ ni iwọn ọdun diẹ sẹhin pe atẹpa ni ọrọ Eleko jẹ ati pe ko tun le gberi nibi kan kan mọ, ṣe lẹhinna ni Baba ṣe arange ti Eleko kanna yi jare Apili rẹ ni ilu Ọba ti aiye gbọ ti ọrun si mọ tobẹ ti awọn eledekede wọnyi fi wọṣin bi ọbẹ Panu. Bawo ni Lọya yi ti ṣe le mọran moran bi o mọ oyun igbin, tabi iwa kaka ki eku ma jẹ sèsé, a fi ṣe awadanu ni o nda Lọya ti o kọ iwe maṣanfani na lamu: ikoko dudu ko gbọ tirẹ o ngbọ ti ẹni ẹlẹni kiri; ohun kan ni a fẹ ki Lọya na mọ on nipe ohun ti *Allah* yio ṣe ko fi han ẹnikẹni; njẹ bi *Prince* Eṣugbayi Eleko ba jẹ ẹgbon Lọya yi nkọ bi yio ti kọwe lo ba kọ yi bi? Bi Lọya yi ba ṣẹgi nigbo, o yẹ ki o fi ọran ro ara rẹ wo, a wi tan o nsọ ohun ti o ni Ofin wi, rọra o, olofin diẹ. o le mọ titi ki o mọ Ofin ju Iwe ofin papa lọ, ẹ jẹ ki a tilẹ bi Lọya yi lere, o di Iwe-ofin melo ni on papa ti ṣe, tabi jijoye afomọ nikan ni o mba kiri?

Awa mọ pe Edumare kanna ti o ṣe aranṣe ti ẹjọ *Prince* Eṣugbayi Eleko bori nilu Ọba tobẹ ti a fi sọpe ki o gba owo irin ẹsẹ lọwọ Ijọba, ṣi wa bakanna fun ṣ'ṣe aranṣe ti yio fi mu Eleko tawa bọ wale laipẹ lọ titi.

Kaka k' Ebi ko p' Ajanaku
Igbẹ l' oju o ti.

---

## ENIA DUDU KO LE DA OHUN KAN ṢE.

Njẹ bi ọro ti awọn Oyinbo yi sọ le ribẹ tabi ko le ribẹ, ki nṣe ti awa papa ko pawọpọ da tọrọtọro ki afi da nkankan silẹ bi a ko le dawole ti ọkọ kikan ka ye wipe ẹlẹgiri nwa ẹniti yio bo mọlẹ, aijigiri wa mu nkankan ṣe tubo pẹlu airi iṣẹ ṣe awọn ọmọ wa, o yẹ ki a mọ pe jijigiri awọn ti o ri iṣẹ jẹ nanlọwọ fun awọn ti ko ri kan ṣe kan, fun ire ara rẹ ati igbẹkẹle ilu rẹ. Nigasikia a ko ri ẹni ti o le ti ara igi tabi ọpe dide bikoṣe ara enia alakeji rẹ. Ọpọ ninu awọn olowo, onisowo lo ti ti ara ẹniti o nṣiṣẹ ni abẹ rẹ dide, ero yi ni ko jẹ ki a le lọ siwaju mọ si rope o to akoko lati fi ero na silẹ larin wa; ẹnyin ẹ wo awọn Oyinbo pẹlu aini ... ti wọn ti wa ṣiṣẹ ni ilu wa, nigbati wọn ba si ti ṣe iṣẹ bi ọdun kan gbogbo nkan apada si rere fun wọn, bi o ko tete ya lẹhin-

gbẹti afi *Motor* tẹ ẹ, owo lo sa ma jẹ, bi Oyinbo ba ti ṣe iṣẹ ọdun marun mẹfa ero ki on le dawa ki on ni owo fun ara on ni yio ma du, omiran a gbe ilu rẹ ko ni wa mọ nitori o ti ri owo to lati ko si *Bank* tabi wọ ẹgbẹ onişowo kan ti yio ma mu ere wa fun jijẹ ninu rẹ ti ti yio fi ku.

Tani o le ṣe didun inu rẹ pe ki o gba Akọwe kan si iṣẹ, ki o jẹ pe akisa tabi aṣọ eleri ni o nwọ wa si ibi iṣẹ, o wa ninu iṣẹ ọdun kini, ikeji sibẹ abi aguntan ko pa aṣọ eşi da ni aṣọ ti o nmu wa si ibi iṣẹ nipa fifaya tabi eri, bẹni a ko ṣe alai fi kun owo iṣẹ rẹ nigbati a ba ri wipe o yẹ; tani jẹ ba Burọda onina, Anti onina rin, o ki yio sọ fun akọwe yi wipe aṣọ onina yi ko ni wọ ibi iṣẹ rẹ. Eyi mu mi ranti ibi iṣẹ kan ni Eko yi pe Akọwe ti ko ba di pali mọ ọrun ki o si fun ijara mo (*Collar and Tie*) bi a ko ba tete da pada Oyinbo tabi Ọga iṣẹ na yio sọ fun pe ko gbọdọ ṣe bẹ wa si ibi iṣẹ ni agogo meji.

Bi ẹgbẹ tabi apapọ Onişowo kan ba ṣẹṣẹ di de ti nwọn ba gba Akọwe kan ni aṣoju wọn ti o ba jẹ pe nigbati a gba akọwe yi si iṣẹ yi ko ni kotu (*Coat*) lọrun, ki ikunsinu ma ṣe si fun wọn wipe wo akọwe ti a gba ni ijẹta yi ẹsẹ ni o ti fi nrin wa si ibi iṣẹ o ti di oni Motor nisisiyi, ẹnyin ko mọ pe iyi ti nyin ni eyi jasi, niwọn igbati ẹ ba ti mbẹ iṣẹ iriju yi wo ni ọna gẹgẹ bi otitọ ti o si yẹ ti ẹ si nro wipe taja t'enia mejeji ko ṣa ju lọwọ

Gẹnnẹ-Boya bi a fi iwọ papa si ibẹ o le gbe ọsan ta fun oru.

Ni ọna keji bi o ba sin jẹ wipe iriju yi jẹ Alagbeda, jẹgudu jẹra ni, ki ẹ ma ṣe jẹ ki eyi ki o mu sisu ba ni ani lati sọ fun iriju na ki o mura ati şiro iṣẹ rẹ nitori ki yio ṣe iṣẹ iriju pẹ mọ, ki a si yọ bi jiga ki a si fi ẹlomiran dipo rẹ nitoripe nipa ifarada ati iforiti ba yi ki ẹgbẹ yi to parọ ẹni meji tabi mẹta ki yio ṣe alai ri ilọ siwaju Ẹgbẹ yi nipa pipa de ẹnire, mo fẹ ki ẹ mọ wipe gbogbo enia ko ni ọta aje. Ẹnyin wo awọn Oyinbo bi wọn ba fi iriju (*Agent*) kan si idi owo nigbati iriju yi ba ṣe iṣẹ odun kan ti wọn ba bẹ iṣẹ rẹ wo ti wọn si ri pe oie ni bi jiga ni wọn yio yọ pẹlu ipalele lori tabi ki wọn fi ṣọwọ si ile onigo, eyi ko ni ki ilẹkun ibi iṣẹ yi ki o ti, logan nwọn a sin ti fi ẹlomiran rọpo rẹ.

Die ninu wa ni o mọ riri ohun ti a npe ni Ẹgbẹ tabi Akoko, nigbati a ba ti ru iwe kiri tabi afi si ode pe ẹgbẹ yio wa ni ibi bayi ni ọjọ bayi ni agogo mẹta abọ, o di agogo marun tabi mẹfa ni o to ma ri ikankan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ ti yio ma wọ si i bo bi igbati (*Railway*) Relwe gun, bi o si ri imiran lode ani on i o tun ranti ijọ ti wọn fi apejọ na si mọ Salamọtu Sabitiyu ti ko gbogbo ero rẹ lọ, ti o sin fi iye denu ti o sọ fun gẹgẹ bi ẹ ti sọrọ si ninu ipade ọjọ na, atuto sọke afoju gba ani iyẹn ko ni wọ rara, gbogbo wa ni a ni lakaiye ọtọtọ kaka ki o wa si apejẹ yi pẹlu imọran tirẹ ki a da ero a lọ lẹmọ ọpa, o nwa idi ilẹkẹ kiri, gẹgẹ bi o ti fi ile iwe s lẹ o ti gbagbe oro ni (*play while you play, work while you work, this is the time of work*) akoko ere ọtọ akoko iṣẹ ọtọ.

AGBA-LẸTU

## *Olusakin's Column.*

**The Venerable Archdeacon Ogunbiyi.**

On Thursday the 9th August, 1928, the Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, LTH., left Lagos to Ile-Ife on pleasure car, by special invitation from Rev. J. S. Adejumo asking him to come and preach Anniversary Sermon in connection with the Lagos Pastorate Association at St. Paul's Church, Aiyetoro, Ile-Ifẹ.

Archdeacon Ogunbiyi hopes to pay a visit to the Alaiyeluwa the Ọni of Ifẹ, Kabiyesi!

**On Holiday.**

Master Gabriel Adeyẹni, Student of the King's College, Lagos, and brother of Prince Adeyẹmi of Ifẹ, is on three months' holiday, as from the 27th July, 1928.

Master Adeyẹni left Lagos for Ile-Ifẹ on Monday the 6th instant to spend part of his holiday, after which, it is understood he will, on his arrival, spend the balance of two months with his Guardian Mr. D. A. Bright before the College re-open.

**Jubilee Of Service.**

EASTER, APRIL 7TH, 1878, TO EASTER, APRIL 7TH, 1928

A Thanksgiving Service has been arranged and will take place at St. Jude's Church, Ebute Metta, on Saturday, the 18th August, 1928, at 4 o'clock p.m., in commemoration of the Fiftieth Anniversary of Rev. James Jameison Pearse's work in the Mission. Preacher—The Right Rev. A. W. Howells, D.D., Assistant Bishop on the Niger.

And afterwards an "At Home" at the Parsonage. Congratulations to Rev. and Mrs. Pearse in advance.

**Departures.**

By the steamer *R.M.S. Abinsi* which sailed this port on Friday the 3rd August, 1928, Masters Gbadebọ Coker and Ọladigbolu Coker, Grand-children of the late Mr. Andrew Wilkinson Thomas, and sons of Mrs. Christiana Ayọdele

Coker, were among the passengers to England; one will take up Engineering Profession and the other Medical Profession.

**Should One Marry His Deceased Wife's Niece?**

ARCHBISHOP OF CANTERBURY VOTES AGAINST BILL.

The Archbishop of Canterbury's last speech in the House of Lords was responsible for the dramatic defeat in the third reading of a private member's which had already passed the House of Commons permitting persons to marry their nephew or niece by marriage.—*Reuter*.

OLUŞAKIN.

## INA WỌLE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dengẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orisi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No 7, Labinjọ Lane

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## LATI ỌWỌ AGBALẸTU.

### IBOSI OWO!

Ninu ọpọlọpọ nkan ti awa enia nsare si kiri ni aiye yi ni owo; ọna pupọ lo si wa ti a fi nle re: ko dede ti eyi t nri be, nigb ti o je re o je agbara kan: a si mọ pe " owo ko si ẹ... a ko sa.. owo ko si obinrin ko pe ọko l' esiki, "ibosi owo!" Ṣugbọn ninu isare bayi, anu ṣe ni pe ọpọlọpọ ibo sa asa fi ofun igi: opo na si p... rek ja ala, ... awọn ẹlomiran ki ọwọ wọn to le tẹ "ẹtu ida ki wọn to bere iku to pa ... aba:" ninu ire ... ẹlomiran nkọ sona ẹlomiran di ero ẹwọn l nipa bayi nwọn ki si le to ẹgbẹ ati ... wọn ... ṣugbọn ju gbogbo re lo, ti ẹlomiran bi si le ... ba, yala nipa ṣiṣubu s' owo ... o, tabi nipa ... jijẹ, tabi nipa ọna miran, o di pe ki o ṣ... na, ki o si ma fe ifẹkufẹ: aṣẹhinwa aṣẹhinbọ, owo yi a kan iyẹ mọ apa, a si folo; o di pe ki olowo tun bẹrẹ si ṣe wahala; eyi fẹrẹ ba owe ... ti o wipe: "owo akọni ẹmode, akara ni yio fi raje," o si ṣoro fun irọfẹ eni bayi ki o lo le ... itẹlọrun. Bi o ni owo ọran, bi o ko ni ọran:—Kilopo?

### AYA BẸRẸ OṢI BẸRẸ.

A le wipe opo tabi iyawo ati ni aya lo tẹle opo ati lowo, a si ri ... ninu awọn ... do wa l'ọkunrin l'obinrin ti o je pe ko si ero meji ti o wa ninu won ju ati gun ole agba yi lo, ilofenrin nipo ... ẹwun awẹn miran, ko si si ehun ti en tele ti a loṣi tõ eyi fun enia ... o to pẹnu rẹ gbe; nitorije bi aya ba ṣẹ ... meta tabi mẹrin lọd ẹlomiran, opo ọpọlọp ni; bi MARY ṣeṣi l'ofin ... e o nlo ile ju si SALLY, o di ...-mi si-emi ... to; bi o ... te'hin jọ si ABẸKẸ, l gan AṢABI a gba, nitoto "o o ni'ṣa, opo ... yọ" melo ni a o la ninu ẹgọ iyọ ki ... u to ta ni? ... ko ni aya fifẹ ni ikan lo je ewo; ṣugbọn ọpọlọpọ okunrin lo wa ti won ko ... ti to ila de, ti nw n de, ti o si nru mọ won loju" ohun ti o mu eyi wa ... i ... auju awa ... tete ni obinrin; nig ati a ... a ... ti pe "owo l'obinrin mo," ibanuje pupọ ni fun irọfẹ awọn oni-kanju bayi nigbati mawo irofe ona ... nbẹrẹ si ta won lori; opin rẹ ni pe olokulo aya a si di ti ẹlomiran iwọ papa a si wa so agbeje ... pẹlu ironu pe ohun ti owo rẹ koi ti to, o lo ... ni igbagbe pe "owo lo won iyawo ... won" gbogbo fuja rẹ ijọ ... ni a si di asan; ni ẹhin enia ko mọ igbati ojo r... a si wa f... —Kilopo?

IN MEMORIAM

In loving memory of our dear friend Miss VICTORIA MAJẸKODUNMI who departed this life on the 10th August 1921.

"Thy will be done".

by her friends

IBIDUN DOHERTY and JANET JOHN.


Disinfectant Soap of
Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home— it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap
Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications.

Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

## Attention! Attention!! Attention!!!

FOR BUYERS IN GENERAL

HAVE YOU BEEN AT

## IWA-JO-WA STORE, (No. 1 & No. 2)

IF NOT, WHY NOT? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else- where The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby!**

*(Again and again, "Gbangba dękun" Kedere bę wo.)*

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scissorses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do.
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
" " Alum,
" " Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.
Seeing is believing;

"*Ganni ya fi ji.*" Irohin ko to afojuba

Apply to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street. Isalęgangan, Lagos,
20, VictoriaStreet, Lagos.

*Cable Address :—*
**Iwajowa Store No. 1.**
45, Princes Street, Lagos.

## Beware of the season.

Use Dr. Skelton's Influenza and Cold Cure strongly recommended for this Owore Season 2/6d.

## That Wonderful Female Pill!

Wireless Female Pills instils new life in women, recommended for all functional disorders peculiar to women. It regulates the system and prevents barreness 4/- per bottle.

## New Life for Men.

Life Tonic Tablet will revitalise you; this wonderful Tablet costs you 3/- only. Get a bottle.

## Yaro! Yaro! Yaro!

No more pain for children cutting teeth, use 'Yaro' Infant's favouaite Preservative. It prevents convulsion &c., &c. 2/3d and 3/3d per bottle.

**Do away with Piles!**

Get rid of Pile that loathsome disease by using:—

Effective Pile Remedy 7/6d
Pile Pills 1/6d
Pile Ointment 2/-

**Kaduna Balm.**

Every Home requires Kaduna Balm, the family Remedy applicable in 100 different ways. 1/-

**Don't grow old whilst you are still Young.**

Dr. De Roos' concentrated Gnittae Vitae will bring you back to Health and Beauty. Recommended for general debility, dimness of sight, shaking of the hands and limbs—miraculous curer £2 2s. (largest size)

**We also stock:—**

Elixir Hydrastin 10/6d
Elixir Avena with Helonias Compound. 10/-
Sacharine 1/- & 1|6d
Male Tonic 10/6d
Cooling Blood Purifier 7/6d
Vibrona Wine 7/6d

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH.

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nje pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işẹ ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aloyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ baje, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

## WHITE'S WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE"

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşe Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyọ, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

### Indents House.

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———— : o : ————

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.